# Ìfarajọ-Èébú nínú Àwọn Àsàyàn Oríkì Yorùbá

Abídèmi. O. Bọ́lárìnwá
Department of Linguistics and African Languages
University of Ibadan, Nigeria
aobolarinwa@yahoo.com

## Àsamọ̀

Ọ̀kan pàtàkì lára lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ni oríkì jẹ́, àwọn onímọ̀ lọ́kan-ò-jọ̀kan ló sì ti walẹ̀ jin lórí oríkì ṣùgbọ́n kò tí sí iṣẹ́ ìwádìí kan gbòógì tí ó jẹyọ lórí ìfarajọ-èèbú nínú oríkì Yorùbá. Láti di àlàfo yìí, iṣẹ́ ìwádìí yìí fi tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ ṣe àtẹ̀gùn láti ṣe àyẹ̀wò àwọn oríṣìí oríkì Yorùbá mẹ́ta tí ìfarajọ-èébú jẹyọ nínú wọn, èyí tí a ṣe àfàyọ wọ́n láti inú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe àti iṣẹ́ àpilẹ̀kọ àwọn onímọ̀. Àwọn oríkì náà ni oríkì orílẹ̀, oríkì àmútọ̀runwá àti oríkì ìlú. Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé gbogbo àwọn ìpèdè tí ó farajọ èébú àti ìtìjú fún àwọn ènìyàn ní àwùjọ Yorùbá ni wọ́n kì í ṣe èébú ṣùgbọ́n tí wọ́n jẹ́ ohun àmúyangàn, ohun ọlá àti ẹ̀yẹ ní ìgbà tí a bá ti sọ ọ́ di oríkì tí a sì fi ń ki àwọn olóríkì. Ohun ti èyí ń tọ́ka sí ni pé, àwọn àṣà àti èrò Yorùbá nípa èébú àti àbùkù máa ń yípadà ní ìgbà tí a bá ṣàmúlò wọ́n gẹ́gẹ́ bí oríkì ní ilẹ̀ Yorùbá, torí kì í ṣe èébú mọ́ ṣùgbọ́n ìtọ́ka sí ìtàn àti ìṣe akọni olóríkì ni.

## Ìfáàrà

Kòṣeémánìí ni oríkì jẹ́ láàrin àwọn Yorùbá, ọ̀kan pàtàkì sì ni pẹ̀lú láàrin àwọn ewì alohùn Yorùbá. Ogún ìbí àwọn Yorùbá ni oríkì èyí lò sì jẹ́ kí ó wà láti ìgbà ìwáṣẹ̀ títí di àsìkò yìí. Àwọn tí ó jẹ́ àrè tàbí àtọ̀húnrìnwá kìí ni oríkì èyí ló sì jẹ́ kí àwọn ọmọ Yorùbá máa tàbùkù irúfẹ́ àwọn ènìyàn tí kò ní oríkì yìí nípa pípè wọn ní "alórúkọ máà lóríkì". Lára àwọn onímọ̀ tí ó ti ṣiṣẹ́ lórí oríkì ni Láṣebìkan (1958), Beir àti Gbàdàmọ́sí (1954), Gbàdàmọ́sí (1961), Atiládé (1974), Awẹ́ (1974, 1975), Ọlátúnjí (1969, 1979, 1984), Babalọlá (2001), Babáyẹmí (1988), Akínyẹmí (1991, 1997, 1999 àti 2004), Barber (1990 àti 19991), Ajíbádé (2001 àti 2009), Olúnládé (2005), Akínselọ́yín (2014), Àjàyí (2014), Adéjùmọ̀ àti Oyèbámijí (2019) àti Bọ́lárìnwá (2019).

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọn ti fún oríkì ní ìtumọ̀, Gbàdàmọ́sí (1959:12) pe oríkì ní àpólà ewì tí a lò láti ṣàpèjúwe tàbí gbóríyìn. Ní ti Adéoyè (1982:41): ó ní oríkì a máa fi ìwà akọni àti akíkanjú hàn, àti pé bí a bá fi pe ọmọ tí a si lò ó pọ̀ mọ́ oríkì ọmọ, orí ẹni a máa wú, àáró a sì máa sọ ni". Láṣebìkan (1958:32) ní tirẹ̀ sọ pé oríkì máa ń sọ ibi tí ènìyàn ti sẹ̀, bí wọ́n ti lágbára tó ní ìdílé wọn, bí wọ́n ti là tó àti oríṣìíríṣìí nǹkan akọni tí wọ́n ṣe gbogbo. Babalọlá, (2001:viii) rí oríkì gẹ́gẹ́ bí ohun tí àwọn Yorùbá máa ń lò láti fi pọ́n ara wọn, nígbà tí Olúnládé (2005:42) sọ pé oríkí máa ń ṣe àfihàn agbára àti ìhùwàsí láàrin àwọn Yorùbá. Adéjumọ̀ àti Oyèbámijí (2019:63) sọ pé oríkì jẹ́ ọ̀nà kan tí àwọn Yorùbá máa ń gbà láti ṣe ìdánimọ̀ pẹ̀lú àwọ́n baba-ńlá wọn àti láti gba ara wọn ní ìyànjú láti jẹ́ akíkanjú bí i tiwọn. Tí a bá wo ohun tí àwọn onímọ̀ sọ nípa oríkì ní òkè yìí ohun tí ó hàn gbangba ni pé gbogbo ìwà àti ìṣe olóríkì ní a ń mú wá sí ìrántí nínú oríkì èyí tí ó sì máa ń mú ìwúrí wá.

Èrò àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ bí Finnegan (1970), Barber (1979 àti 1988), Ọlátúnjí (1984), Ajàyí (1984) Akínyẹmí (1991 àti 2004), Ògúndèjì (1991) Adéjùmọ̀ àti Oyèbámijí 2019 àti Àránsì (2019) kò yàtọ̀ sí ohun tí Gbàdàmọ́sí sọ pé "oríkì ni àpólà ewì tí a lò láti ṣàpèjúwe tàbí gbóríyìn". Ohun tí ó hàn gbangba ni pé oríkì máa ń ṣe àfihàn orírun olóríkì, ìrísí, ìṣesí, ìhùwàsí rẹ̀ àti bí ó ṣe lágbára tó. Bákan náà ni oríkì máa ń tọ́ka sí ohun tí ẹ̀dá ènìyàn kan nífẹ̀ẹ́ sí, iṣẹ́ tí ó ń ṣe àti àwọn ohun tí ó jẹ́ èèwọ̀ fún un. Oríkì kò dúró sójú kan bí odò adágún, ojoojúmọ́ ló ń fẹjú sí i, bí ìṣe akin olóríkì bá ṣe ń pọ̀ sí i náà ni oríkì rẹ̀ yóò máa pọ̀ sí i. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí Lindon (1990:208) sọ pé:

> Oríkì is not a ready made poem, but is composed piecemeal over the long period of subject's life. Single epithets or sentence in hyperbolic language are spontaneously coined about the subject by his contemporaries friends and foes alike-who have had a chance of observing him at close quarter.

> Oríkì kìí ṣe ewì tí a ṣẹ̀dá tán lọ́jọ́ kan, ṣùgbọ́n ó jẹ́ èyí tí a ń sẹ̀dá díẹ̀ díẹ̀ fún ìgbà pípẹ́ nípa ìgbésí ayé olóríkì. Àlàyé kan tàbí gbólóhùn àsọdùn tí a ṣẹ̀dá láti inú ẹni wá nípa ẹni tí a ń kí láti ọwọ́ àwọn ọ̀rẹ́ tàbí ọ̀tá olóríkì àwọn tí ó ti ní àǹfààní láti ṣe àwòfín rẹ̀ pẹ́kípẹ́kí.

Bí o ti jẹ́ pé oríkì a máa dá lórí ìtàn ìran tàbí ìdílé àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tí ó farasin tí ó ti sẹlẹ̀ nínú ayé ẹni tí a ń kì, ẹni tí ó bá fẹ́ ní òye ohun tí oríkì ẹnìkan túmọ̀ sí nígbà náà gbọdọ̀ jẹ́ ẹni tí o fara balẹ̀ kí ó sì mọ ohun tí ó bí ìtàn inú oríkì tí ó gbọ́. Àfikún ìtàn èyí tí ó máa ń wọ inú oríkì láti ìgbà-dé-ìgbà ni ó máa ń fa ìṣípòpadà àti oríṣìí ìtumọ̀ èyí tí ó máa ń jẹyọ nínú oríkì.

Àbùdá márùn-ún pàtàkì ni Ọlátúnjí (1984) fún oríkì. Àwọn àbùdá náà ni: ìṣọdorúkọ, lílo ọ̀rọ̀ ìtọ́kasí ẹbí ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà, títọ́ka sí ẹni tí a ń kì ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà, yíyán ìtàn fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́ àti àìdọ́gba ìhun àti àkóónú. Àrífàyọ tí a ṣe nípa àbùdá

oríkì ni pé ọ̀kanòjọ̀kan ọ̀nà ní ó máa ń gbà láti tọ́ka sí olóríkì èyí tí ó sì máa ń mú ìtàn sísọ dání. Nígbà náà bí a bá fẹ́ mọ ẹnìkan ní kíkún oríkì irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ni a ó kíyèsí.

## Ipa Oríkì

Ipa pàtàkì tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ni oríkì ń kó láàrin àwọn Yorùbá. Ìdánimọ̀ àti ọ̀kan lára àmì ìdánimọ̀ ni orìkì jẹ́, èyí nìkan kọ́, orísùn ìwúrí àti àmúyangàn tún ni fún ìran Yorùbá. Ó fẹ́rẹ̀ máà sí ewì alohùn àti àpilẹ̀kọ Yorùbá ti a kìí ti í ṣe alábàápàdé oríkì, onírúurú ọ̀nà ni oríkì lè gbà wáyé: lákọ̀ọ́kọ́ òbí lè ki ọmọ rẹ̀ ní ìgbà tí ó bá jí ní ní òwúrọ̀ láti mú orí rẹ̀ wú. Bákan náà, ni tí ó bá ń lọ ìrìnàjo ó lè kì í láti fi ṣe kóríyá fún un. Èyí níkan kọ́, wọ́n tún máa ń ki ọmọ tí ó bá ń ṣe ìgbeyàwó ní ilẹ̀ Yorùbá láti rán an létí àwọn ìṣe akin àwọn baba ńla rẹ̀. Àwọn onírárà tàbí akígbe ọba náà máa ń ki ọba ní ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Apohùn tàbí Alágbe máa ń ki oríkì níbi ayẹyẹ lọ́lọ́kanòjọ̀kan ní ilẹ̀ Yorùbá, bí àpẹẹrẹ ìsílé, ìsọmọlórúkọ, ìsìnkú àgbà àti ìgbeyàwó. Ọlátúnjí (1984:71) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ní ìgbà tí a bá ń ki oríkì ẹnìkan onírúurú orúkọ tí irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ń jẹ́ ni a máa ń ṣàmúlò láti kì í. A máa ń sọ̀rọ̀ nípa ìdí àti ìtumọ̀ tí orúkọ olóríkì ní, torí gbogbo orúkọ ló ní ìtumọ̀ àti ìdí tí a fi ń sọ wọ́n ní ilẹ̀ Yorùbá, èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé “Ilé làá wò, ká tó sọ ọmọ ní orúkọ”, Bákan náà ìrísí olóríkì tí ó jẹ́ àwọn àbùdá àdámọ́ rẹ̀ pẹ̀lú ìṣesí àti ìhùwàsí olóríkì tí ó jẹ́ bárakú fún un wà lára ohun tí wọ́n máa ń ṣàmúlò láti kì í. Èyí nìkan kọ́ wọ́n tún máa ń tọpasẹ̀ olóríkì dé ọ̀dọ̀ àwọn bàbá-ńlá rẹ̀ àti àwọn ìwà akin tí a mọ̀ wọ́n mọ́, ní ìgbà tí a bá wá ki oríkì ẹnìkan dáradára tí a sì sọ̀rọ̀ kíkún nípa rẹ̀, èyí máa ń jẹ́ kí orí ẹni tí a ń kì náà wú. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni a lè gbà ki ènìyàn, ó lè jẹ́ ní ìlànà àrángbọ̀, ìsàré tàbí orin, ọ̀gàngàn ipò tí oríkì bá ti jẹyọ ni yóò sọ ọ̀nà tí a ó gbà ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Fún àpẹẹrẹ, bí ó bá jẹ́ òbí kan ni ó fẹ́ ki ọmọ rẹ̀ tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ dé láti ìrìnàjo kan, ìlànà àrángbọ̀ ni yóò gùnlé láti kì í, ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ ní àsìkò ayẹyẹ pàtàkì tàbí ọdún ìbílẹ̀ kan ni, a lè ṣàmúlò ìsàré tàbí orin láti ki oríkì. A tún le lo ìlù láti ki oríkì ní ilẹ̀ Yorùbá, bákan náà ni àwọn ọba alayé ní ilẹ̀ Yorùbá máa ń ní àwọn apohùn tàbí akígbe ọba tí wọ́n máa ń fi ìlù jí wọn ní àràárọ̀.

Gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1984:71) ṣe sọ oríṣìíríṣìí oríkì ni ó wà ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn oríkì náà ni: oríkì orílẹ̀, oríkì ọba aládé, oríkì àwọn òrìṣà, oríkì àdájẹ́, oríkì ewéko àti ẹranko. Ní ìgbà tí a bá ń ki oríkì ẹnìkan gbogbo ohun tí yóò ṣàpèjúwe àwọn àbùdá olóríkì ni a ó máa tọ́ka sí, àwọn bí i ohun akíkanjú tí ó ti ṣe, ìwà akin rẹ̀, ìdílé tí ó ti jáde, agbara oògùn tí ó ní àti ìmọ̀ọ́nṣe rẹ̀ nínú iṣẹ́ tí ó yàn láàyò. Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa oríkì ohun tí ó hàn gbangba ni pé ẹni tí ó ń ki ènìyàn kan mọ ẹni náà dáradára ni kí ó tó lè kì í, bẹ́ẹ̀ ni ajọṣepọ̀ àti àgbọ́yé wà láàrin olóríkì, ẹni tí ó ń kìí àti àwọn tí ó jẹ́ olùgbọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. Ọ̀pọ̀ ìgbà ní yíyán ìtàn fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́ sì máa ń jẹyọ èyí tí ó jẹ́ pé àwọn olùgbọ́ tí kò ní ìmọ̀tẹ́lẹ̀

nípa ohun tí apohùn ń sọ nílò àlàyé kí wọ́n tó lè mọ pàtàkì oríkì yìí tàbí kí ìtumọ̀ rẹ̀ tó lè hànde.

Gẹ́gẹ́ bí Babalọlá (1966:24) ṣe sọ àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kíki oríkì àwọn baba-ńlá ẹni dáradára lẹ̀ mú kí inú wọn dùn ní àjùlé ọ̀run kí wọ́n sì rọ òjò ọ̀pọ̀ ìbùkún léni lórí, bákan náà, kíki oríkì ẹbí, tàbí orílẹ̀ ẹni dáadáa máa ń mú inú ẹni dùn, bí ènìyàn bá tilẹ̀ wà wà lájò, kía ni àárò yóò máa sọ ni, èyí ń fi pàtakì orikì láàrin àwọn Yorùbá múlẹ̀ sí i.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kíki oríkì ẹni lè mú orí ẹni wú tàbí kí ó mú orí àwọn baba ẹni wú láti tú ìbùkún lé ni lórí. Ẹ̀rí nínú àwọn oríkì kan ń fi hàn pé ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ tí ó ń jẹyọ nínú oríkì ń tọ́ka sí àléébù olóríkì, tàbí èébú tó wà lára ìran olóríkì. Nígbà míràn ni àwọn tí kò mọ ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ oríkì tí a fi ki olóríkì kan yóò má wo àwọn ìpèdè kan nínu oríkì bẹ́ẹ̀ bí èébú ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ àwọn oríkì wọ̀nyí ń ṣe ìtọ́kasí ìtàn ìran àti ìṣe akọni àwọn olóríkì ni.

Ìdí nìyí tí a óò fi ṣàyẹ̀wò ìfarajọ-èébú nínú àwọn àsàyàn oríkì Yorùbá. Àwọn oríkì tí a ó máa yẹ̀wò ni oríkì-orílẹ̀ Àágberí, Ajíbógundé, Olúkòyí àti Arẹ̀sà, oríkì ìlú Ìkàrẹ́, Àkúrẹ́, Ìkirè àti Ìbàdàn, oríkì àmútọ̀runwá Oyèrìndé, Ìgè, Òjó àti Aasà. Tíọ́rì tí a yàn láàyò ni tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀.

## Tíọ́rì Àmúlò: Tíọ́rì Ìfìwádìí-Sọ̀tumọ̀ (Hermeneutics)

Ní ọ̀nà àti jẹ́ kí iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítiréṣọ̀ kan ní ìtumọ̀ àti kí àwọn lámèétọ́ lè ṣe ìdájọ́ tí ó tọ̀nà, ó yẹ láti ṣàmúlò tíọ́rì lítíréṣọ̀ kan èyí tí a rò pé ó péyé fún ìtúpalẹ̀ irú iṣẹ́ ọnà bẹ́ẹ̀. Tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ (Hermeneutics) ni a wòye pé ó dára fún iṣẹ́ ìwádìí yìí. Edmund Husserl ni ó dá tíọ́rì yìí sílẹ̀ ní ọdún 1964. Inú tíọ́rì ìfojú-inú-wo-ẹ̀mí ara-nǹkan (phenomenology) ni tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ ti jáde gẹ́gẹ́ bí Riccocur (1991:25) sọ. Ohun ti tíọ́rì yìí fúnka mọ́ ni pé ohun gbogbo tí ó wà láyé ko dá wà láìní nǹkan ṣe pẹ̀lú ènìyàn. Àlàyé Husserl ni pé nígbà tí ènìyàn bá fi ojú inú wo nǹkan ni ó lè mú kí àṣepọ̀ wà láàrin èrò ọkàn ènìyàn àti ohun tí ó ń wò àti pé ohunkóhun tí kò bá sí nínú ìrírí ènìyàn tí kò lè fi ojú inú wò, kò yẹ kí ó fi ààyè gbà á nínú ọkàn rẹ̀.

Klein, Blomberg àti Hubbard (1993:4) ṣe àlàyé pé láti inú èdè Gíríkì ni "hermeneutics" tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe, tí ó sì túmọ̀ sí "láti ṣe àlàyé, ṣe ògbufọ̀ tàbí túmọ̀" tí ọ̀rọ̀ orúkọ rẹ̀ sì jẹ́ "hermeneia" tí ó túmọ̀ sí fífún nítumọ̀ tàbí títúmọ̀ èdè ti jáde. Tíọ́rì yìí ní ṣe pẹ̀lú ìtumọ̀ nípa àgbékalẹ̀ òfin gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ sáyẹ́nsì nítorí náà Ramm (1970:2) pè é ní "science of interpretation" èyí tí í ṣe fífún nítumọ̀ ní ìlànà sáyẹ́nsì, èyí nìkan kọ́, ó tún gbà pé ó ní í ṣe pẹ̀lú ẹ̀kọ́ nípa ẹ̀dá nítorí àmúlò àwọn òfin tí ó rọ̀ mọ́ ọn; kì í ṣe ohun tí ó lọ tààrà.Ohun tí tíọ́rì yìí rọ̀gbọ̀kú lé ni láti tọ́ka sí àwọn ọnà tí ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin èrò oníṣẹ́ ọnà àti olùgbọ́ yóò ṣe dínkù bí a kò bá lè mú wọn kúrò.

Ìgbàgbọ́ àwọn agbátẹru tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ ni pé ìtumọ̀ iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ kan kò sí lójú kan àti pé iṣẹ́ olùgbọ́ ni láti sà wọ́n jọ, kí kókó-ọ̀rọ̀ inú iṣẹ́ ọ̀nà bẹ́ẹ̀ lè yọ síta. Tíọ́rì yìí wúlò fún iṣẹ́ yìí nítorí pé ó fún olùgbọ́ ní

àǹfààní láti ṣe ìdájọ́ lórí iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ kan tàbí òmíràn láìkọbi ara sí ìtumọ̀ tí ó bá wà ní ọkàn oníṣẹ́-ọnà bẹ́ẹ̀. Èròǹgbà tíọ́rì yìí ni pé bí olùgbọ́ bá mú ìrírí, èrò àti ìmọ̀ rẹ̀ lò láti túmọ̀ iṣẹ́ ọnà kan, ìtumọ̀ irú olùgbọ́ bẹ́ẹ̀ kò le yàtọ̀ púpọ̀ sí èyí tí ó wà lọ́kàn oníṣẹ́-ọnà gan-an nítorí pé inú àwùjọ kan náà ni wọ́n ti wá. Tíọ́rì yìí tún sọ pé ìtumọ̀ iṣẹ́ kan kò ṣe é rí lójú kan ṣoṣo bẹ́ẹ̀ gẹ́lẹ́ ni àwọn ìtumọ̀ inú àwọn oríkì rí, àfi bí a bá wádìí ìṣẹ̀lẹ̀ inú wọn ni a tó lè rí ìtumọ̀ tí ó péye fún wọn.

## Ìfarajọ- Èébú bí ète Ìgbóríkì kalẹ̀ láwùjọ Yorùbá

Èébú ni èdè àbùkù tí a le fi ṣáátá tàbí pẹ̀gàn ènìyàn kan. Èyí tí ó ń ṣe àpèjúwe ìrísí, ìṣesí tàbí ìhùwàsí irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀, kìí ṣe ẹni tí o bá ṣẹ̀ nìkan ni a lè bú, èébú máa ń jẹ jáde nínú àwàdà ṣíṣe pẹ̀lú. Bí èébú bá wá wáyé ní ọ̀nà àwàdà, ó túmọ̀ sí pe ẹni tó ń bú ni àti ẹni tí à ń bú náà mọ̀ pé àwàdà lásán ni. Kò sí ẹni tí ọmọ aráyé kò lè bú, kò sí ipò tí ẹ̀dá ènìyàn lè wà tí ó kọjá ẹni tí wọ́n ń bú, ní ìgbà mìíràn a lè ra èébú kan ti kìí ṣe ti ènìyàn fun un, bẹ́ẹ̀ ni àwọn èébú kan wà tó jẹ́ pé rẹ́gí ni ó bá ẹni tí wọ́n ń bú mu. Ní ìgbà tí àwọn ènìyàn kan ba sọ ìsesí, ìrísí, tàbí ìhùwàsí wọn èyí tí àwọn ènìyàn lérò pé wọ́n fi ń tàbùkù tàbí yẹpẹrẹ wọn di ohun iyì àti ẹ̀yẹ, ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé àwọn ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí yìí ń ṣàfihàn ìṣe akọni àtí ìtàn ìran baba ńla àwọn olóríkì ni, èyí tí ó sì yẹ fún àmúsògo.

Gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nu bà á ṣaájú, ìfarajọ-èébú a máa jẹyọ nínú oríkì Yorùbá, ìdí ni pé nígbà tí ìwà olóríkì tàbí ìran rẹ̀ bá tako àṣà ìwà ọmọlúàbí láwùjọ Yorùbá, iyì ni olóríkì fi í ṣe torí ó ń ṣe àfíhan agbára, ìṣe akọni àti ìtàn ìran wọn ni. Ní báyìí a ó máa ṣe àgbéyẹ̀wò ohun tí àwọn onímọ̀ sọ nípa èébú.

Oríṣìí èébú mẹ́ta ni Bariki (2009 àti 2011) sọ̀rọ̀ nípa wọn, èkínní ni èébú tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ẹ̀yà, èkejì ni èébú tí ó ni í ṣe pẹ̀lú ẹ̀dá ohunkóhun, ní ìgbà tí ẹ̀ẹ̀kẹta jẹ́ èébú tí ó ní í ṣe pẹ̀lú àwùjọ.

Applauso (2010) sọ̀rọ̀ nípa bí àwọn tí ó wà ní ipò gíga àti àwọn tí ọjọ́ orí wọn wà láàrin ogójì àti àádọ́ta ọdún ní Ítálì ṣe ń ṣàmúlò èdè abínibí wọn láti bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìbàjẹ́ kan ní pàtó tí ẹnikan, ẹgbẹ́ tàbí àwùjọ kan hù. Àjọṣepọ̀ tó wáyé láàrin èébú àti ẹ̀rín jẹ́ idà olójú méjì; àkọ́kọ́ ní bíbu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìbàjẹ́ kan, èkejì ní ṣíṣàmúlò ẹ̀rín àti ẹ̀fẹ̀ láti bá wí. Èébú yìí ni olùwádìí sọ pé àwọn ènìyàn tí a dárúkọ saájú yìí máa ń lò fún ìbáwí láti sọ̀rọ̀ àti láti lòdì sí ìwà àìtọ́ kan lọ́nà àti wá ọ̀nà àbáyọ sí wàhálà tí ìwà àìṣedéédé yìí ti dá sílẹ̀.

Kodah (2012) fi ojú-ìwòye lítíréṣọ̀ ṣe ìtúpalẹ̀ èébú, ó ṣe àfàyọ àwọn oríṣìíríṣìí ìpele èébú tí ó jẹyọ láti ara àwọn ẹ̀dá ìtàn àròsọ tí ó gbéyẹ̀wò. Ó tẹ̀síwájú pé àtakò tàbí ìbínú ni ó máa ń ṣe atọ́nà fún èébú àti pé èébú dúró bí í àwòjíji fún ọkàn èyí tí a ń lò láti ṣàfihàn ìjákulẹ̀ tàbí ìbínú gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìdáàbòbò ẹ̀dá tàbí ìwà rere ẹni.

Ọpárìndé aayr (2017) ṣe àfiwé èébú nínú èdè Afíríkà méjì, Isizulu tí wọ́n ń sọ ní gúsù orílẹ̀èdè Áfíríkà àti Yorùbá tí wọ́n ń sọ ní gúsù ìwọ̀ oorùn Nàìjíríà.

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣàfihàn pé èébú máa ń jẹyọ láàrin àwọn tí ó sọ èdè méjèèjì yìí ní ìgbà tí aáwọ̀ tàbí ìjà ọ̀rọ̀ bá wáyé láarin wọn. Wọ́n tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé èébú máa ń jẹ jáde ní àyíká ọ̀rọ̀ kan bẹ́ẹ̀ ni ó gbáralé àṣà. Ìkádìí iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé ìjọra àti ìyàtọ̀ tó lóòrìn ló wà láàrin àwọn afọ̀ èébú tí àwọn olùwádìí gbé yẹ̀wò nínú èdè Isizulu àti Yorùbá. Èyí túmọ̀ sí pé ohun tí ó jẹ́ èébú nínú àṣà kan lè má jẹ́ èébú nínú àṣà mìíràn.

Akínyẹmí (2004) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀nà rere ni àwọn akéwì ọba máa ń gbà bu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà ìbàjẹ́ àwọn ọba alayé. Akínyẹmí jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé iṣẹ́ àwọn akéwì ọba yìí ni láti máa ki ọba ẹni tí ó jẹ́ olórí wọn. Ní ìgbà tí ó lo àwọn akéwì ní àfin aláàfin Ọ̀yọ́ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ó ṣàlàyé pé àwọn akéwì yìí máa ń gba ọ̀nà èrọ láti ṣe ojúṣe wọn tí ó lágbára yìí. Akínyẹmí tún sọ ọ́ di mímọ̀ pé bí a kò bá túmọ̀ àwọn ewì àwọn akéwì ọba yìí bí ó ṣe yẹ, torí ọ̀nà ẹ̀rọ tí wọ́n ń gbà gbé ọ̀rọ̀ wọn kalẹ̀, yóó sòro láti rí ìtumọ̀ èyí tí a fi lè so ó mọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń lọ ní àwùjọ. Ní ìgbà tí àwọn akéwì ọba bá fẹ́ bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìbàjẹ́ kan tí ọba hù, dípò kí wọ́n sọ ọ̀rọ̀ sánpọ́nná, ṣe ni wọ́n máa ń ṣàmúlò ìyántàn-fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́ àti àkànlò-èdè láti jẹ́ iṣẹ́ wọn. Bí àwọn akéwì ọbạ ṣe ń gbóríyìn fún ọba náà ni wọ́n tún ń pe àkíyèsí rẹ̀ sí àwọn ohun tí ó bá ṣe tí ó kù díẹ̀ káàtó torí wọ́n kò gbàgbé pé ọlọ́pàá àwùjọ ni àwọn jẹ́. Akínyẹmí wá gba àwọn akéwì òde òni tí wọ́n sábà máa ń kéwì láti gbóríyìn fún ìjọba, èyí tí kò ṣe àǹfààní kankan fún àwọn ara ìlú láti kẹ́kọ̀ọ́ lára àwọn akéwì yìí tí wọ́n ń gbóríyìn fún ọba tí wọn kò sì tẹ̀tì ní jíjẹ́ ọlọ́pàá ìwà àwùjọ.

Akínṣelọ́yín (2014) ṣiṣẹ́ lórí ìtakóra nínú oríkì Yorùbá tí ó jẹ́ àdájẹ́, níbẹ̀ ni ó ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìtakora tí ó jẹyọ nínú onírúurú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ nínú oríkì. Ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé lílo ìtakora nínú oríkì kò yí òtítọ́ po, ṣùgbọ́n ó jẹ́ irinṣẹ́ tí àwọn oníṣẹ́ ọnà alohùn tàbí ti àpilẹ̀kọ máa ń mọ̀ ọ́n mọ̀ lò nípa dída ojú ọ̀rọ̀ tí yóò mú ìrònú tí ó jinlẹ̀ dání kọ ara wọn. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé ìtakora jẹ́ ohun èlò pàtàkì lọ́wọ́ àwọn oníṣẹ́ ọnà láti fi èrò wọn hàn tàbí bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìbàjẹ́ kan láwùjọ láì jẹ́ pé wọn bọ́ sí inú wàhálà kankan.

**Ìfarajọ-Èébú gẹ́gẹ́** bí o **ṣe jẹyọ nínú àwọn àsàyàn Oríkì Yorùbá**

Gẹ́gẹ́ bí Babalọlá (2001:39) ṣe sọ, ògbólógbòó adáhunṣe àti ẹlẹ́bọ́lóògùn ni baba-ńlá baba àwọn ìran Ààgberí. Orúkọ àpèjá ààgberí sì ni: A-ri-akoto-kó-wọn-sí-gbà-eri, èyí tí ó túmọ̀ sí pé wọ́n gbówọ́ débi pé wọ́n máa ń sọ àwọn ọ̀tá wọn di eèrà, tí wọ́n sì máa ń sọ wọ́n sí inú kòtò. Àyọlò ìsàlẹ̀ yìí ń ṣàfihàn síwájú sí i bí àwọn ìran Ààgberí ṣe gbówọ́ tó:

Ọmọ a lẹ́bọ-tí-yóò-fàparò rú
Ilé ọ̀hun jọ’lé ọ̀rẹ́ mi
Tí ń bá ń lọ ilé àwọn baba mi
Ọmọ a’lẹ́bọ-tí-yóò-fàparò rù
Ọmọ kúkú-sa-orí ọmọ ò sa-ilẹ̀-saàgùn
Bàbá mi l’óhun tí yóò f’àparò ṣe

Ọmọ A-rórí-àparò gúnṣẹ
Ọmọ A-f'ìyàngì-àparò soògùn…
Babalọlá (2001:33)

Láìṣe àní àní, àyọlò òkè yìí fi àwọn ìran Àágberí hàn gẹ́gẹ́ bí olóògùn, ẹni tí ó mọ ewé àti egbò, tí ó sì lè fi ewé àti egbò yìí dá bírà tí ó bá wù wọ́n.

Ìfarajọ-Èébú jẹyọ nínú oríkì orílẹ̀ Àágberí ìsàlẹ̀ yìí:
Bí n bá ń lọ ilé àwọn baba mi, mo mọ le wọn
Ọmọ bá mẹ́kùn lagbàlá
Gbówú Olúgẹ, ọmọ bá méwúrẹ́ so ni gbangba oko
Ojú ewúrẹ́ le bà m'lẹ́rù ju tẹkùn lọ
Òní ni n ó lọ rèé jó òògùn
Ọ̀la mà lọọ jó oògùn
Ọ̀túnla má lọọ dán oògùn wò
Jọ́ mẹ́rin mà wo bí yóò ti jẹ́ sí
Tó bá di'jọ́ márùn-ún
Alárúgbọ́ ó p'arúgbó è mọ́, baba mi ń bọ̀
A-fòjìngòdò-gb'árúgbó alárúgbó-re nú-ìgbẹ́-
Lọ- rèé, jóògùn àgàn
(Babalọla 2001:35)

Bí a bá wo ìlà méjì tí ó gbẹ̀yìn nínú oríkì orílẹ̀ Àágberí òkè yìí, ìṣesí àwọn Àágberí yìí tako ìwà ọmọlúàbí láwùjọ Yorùbá èyí ni pé àwọn Yorùbá kò faramọ́ ìjínigbé àti ìpànìyàn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ ìṣègùn jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára iṣẹ́ àkọ́ṣe àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí wọ́n sì gbàgbọ́ pé Ọlọ́run kò kọ aájò, síbẹ̀ wọ́n lòdì sí kí a máa ṣe ẹ̀dà ènìyàn ní ìjàmbá, ìpalára tàbí pé kí a dá ẹ̀mí ènìyàn légbodò. Bí àwọn Yorùbá ṣe ni ìmọ̀ nípa ìṣègùn tó, wọ́n gbàgbọ́ pé gbogbo agbára jẹ́ ti Ọlọ́run àti pé rere ló pé. Nítorí náà, àwọn Yorùbá kò faramọ́ kí a máa gbé ènìyàn jóògùn. Ohun ìtìjú àti àbùkù ni kí a sọ pé baba-ńlá ènìyàn jẹ́ ẹni tí ó ń lọ gbé arúgbó alárúgbó lọ inú ìgbẹ́ lọ jóògùn. Ṣùgbọ́n ní ọ̀gangan ipò tí ìpèdè yìí ti jẹyọ, àwọn olóríkì, ìyẹn ìran Àágberí kò kà á sí ìpèdè àbùkù, ohun ìwúrí ni wọ́n kà á sí. Torí ìwà akin, ìgboyà, ìmọ̀ọ̀se àti ìjáfáfá àwọn baba ńlá wọn ni wọ́n ń tọ́ka sí. Ní ọ̀gangan ipò tí àwọn ìsẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí ti jẹyọ wọ́n kò rí oríkì yìí mọ́ gẹ́gẹ́ bí èébú rárá, ṣùgbọ́n wọn rí i gẹ́gẹ́ bí ohun àmúṣògo àti àmúyangàn, èyí ni pé wọ́n ti sọ ohun tí ó jẹmọ́ èébú yìí di ọlá tórí ó mú gbogbo ìṣe àti ìwà akọni àwọn baba-ńlá wọn wá sí ìrántí.

Ìfarajọ-Èébú náà jẹyọ nínú oríkì orílẹ̀ Abógúndé, gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí:

Èmí ò lè ṣe kí n má pè é o
Ó wáá jọ ilé àwọn baba mi

Ó jọ'lé Ògúnjùmọ̀bí Alóṣòópọ̀bọ
Ó jọ'lé Afẹ́bíọyẹ́ o, Ọ̀jẹ́dìran
Àtàndá ab'idàá- jẹ̀jẹ́ èèyàn (Babalọlá 2001:130)

Jagunjagun tí ó gbójú ni baba-ńlá àwọn ìran Ajíbogun, a sì mọ̀ pé tí jagunjagun ba ń lọ sí ogun ní ilẹ̀ Yorùbá ohun méjì ni o lè ṣẹlẹ̀, jagunjagun lè bógun lọ tàbí kí o ja àjàṣẹ́gun, kí ó ko ẹrú, kí ó sì kó ẹrù wá sí ilé, fún ìdí èyí gbogbo ipá àti agbára tí àwọn jagunjagun yìí bá ní, ni wọ́n máa ń sà láti rí i pé ogun kò borí wọn. Nínú ìlà tí ó kẹ́yìn nínú àyọlò láti inú oríkì orílẹ̀ Ajíbógun a rí i pé wọn kí àwọn ìràn yìí gẹ́gẹ́ bí apànìyàn, "Àtàndá abidàá jẹ̀jẹ̀ èèyàn, èyí túmọ̀ sí pé ní ìgbà tí àwọn ìran yìí bá ń jagun ọ̀pọ̀lọpọ̀ èèyàn ni o máa ń ti ọwọ́ idà wọn subú lójú ogun, èyí tí o si di ìbẹ̀rù bojo fún àwọn ènìyàn, tí wọ́n sì ń bẹ̀rù àwọn ìran yìí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwùjọ rí àwọn ìran Ajíbógun gẹ́gẹ́ bí ìkà àti aláìláàánú ènìyàn, èyí kò rí bẹ́ẹ̀ torí akíkanjú ni a mọ ẹni tí ó lọ sí ogun sí torí ojo àti ọ̀lẹ ko le lọ ojú ogun. Èyí nìkan kọ́, àwọn ogun kan wà tí ó jẹ́ àìgbọdọ̀ má jà nítorí náà, ní ìgbà tí a bá ń kí wọ́n pẹ̀lú oríkì òkè yìí a ń fi wọ́n hàn bí alágbára àti akíkanjú lójú ogun ni, ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń yọ̀ ṣẹ̀ṣẹ̀ tí wọn yóò sì máa ná akéwì ní owó torí pé orí wọn ń wú, wọ́n ṣì sọ èyí di ohun ẹ̀yẹ àti àmúsògo.

Nínú oríkì ìran Olúkòyí, bí àwọn olóríkì náà ti lákíkanjú tí wọ́n sì jẹ́ alágbára tó, àwọn akéwì kò sàì mẹ́nu ba èébú tó rọ̀ mọ́ ìran wọn:

Àjàkẹ́rùmọ̀lú ọmọ olè ti í jẹ́ tefétefé
Ọmọ ogun lọ́sàn-án, ọmọ olè lóru
Ogun ò lè pọ̀ tó báyìí kí ẹ má folè díẹ̀ kún un
(Babalọlá 2001:44)

Nínú oríkì òkè yìí, akéwì ṣe àfihàn àwọn ìran Olúkòyí gẹ́gẹ́ bíi jagunjagun tí ó fi olè jíjà kún un. Bẹ́ẹ̀ tí a bá wo àwùjọ Yorùbá, àwọn ẹ̀yà Yorùbá lòdì sí olè jíjà. Bákan náà ni wọ́n gbàgbọ́ pé ènìyàn nílò láti ṣe iṣẹ́ kí ó lè jàre òsì. Lára ẹ̀kọ́ ilé tí àwọn Yorùbá máa fi ń kọ ọmọ wọn láti kékeré ni ìwà ọmọlúàbí àti ìtẹ́lọ́rùn, ẹni tí ó bá jẹ́ olè ni àwùjọ Yorùbá kà sí aláìnítẹ́lọ́rùn àti olójúkòkòrò. Kìí ṣe ẹni tí ó jalè nìkan ni wọ́n máa ń tàbùkù ní ilẹ̀ Yorùbá àwọn ẹbí olè pàápàá máa ń di ẹni ìwọ̀sí láwùjọ, fún ìdí wọ̀nyí, àwọn ènìyàn kìí fi ojú ire wo olè ni ilẹ̀ Yorùbá. Bí a bá wo bí a ṣe ń kí àwọn ìran Olúkòyí ni ọmọ ogun lọ́sàn-án, olè lóru yìí, ó farajọ èébú tí ó ní í ṣe pẹ̀lú àwùjọ tí ó sì yẹ kí ó jẹ́ ohun ìtìjú fún wọn ṣùgbọ́n kò rí bẹ́ẹ̀, pẹ̀lú inú dídùn àti ìwúrí ni wọ́n fi máa ń náwó fún àwọn tó bá ń kì wọ́n. Èyí rí bẹ́ẹ̀ torí pé gbogbo oríkì tí akewí fi kí wọ́n ní òkè yìí ó fi ń gbóríyìn fún wọn ni torí ogun tí wọ́n ń jà yìí ti sọ wọ́n di olókìkí àti ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ èyí tí ó ti dá jìnnìjìnnì sí àwọn ọ̀tá wọn lára. Ní ti olè tí a sọ pé àwọn ìran Olúkòyí fi kun ogun jíjà, kì í ṣe olè kólékólé ṣugbọ́n arẹwà obìnrin tí wọ́n bá rí ní ìlú tí wọ́n ti lọ jagun ní wọ́n máa ń mú wá ilé láti fi ṣe aya.

Bákan náà, dandan ni kí àwọn tí ó bá jagun ṣégun kó ìkógun wá ilé gẹ́gẹ́ bí èrè ogun tí wọ́n jà, tí wọ́n sì borí. Fún ìdí èyí ní ìgbà tí akéwì bá ń ki àwọn ìran Olúkòyí ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá pẹ̀lu oríkì òkè yìí kì í ṣe èébú mọ́ bí kò ṣe ohun àmúyangàn torí ìṣe àti ìwà akíkanju ìran wọ́n ni akéwì ń yòǹbo wọn fún. Torí kíkó ẹrú àti ẹrù wá sí ilé láti ojú ogun kì í ṣe olè jíjà ṣùgbọ́n ohun tí ó tọ̀nàtí ó sì ń ṣe àfihàn ìṣẹ́gun.

Nínú oríkì ìran Arẹ̀sà, a tún rí àpẹẹrẹ ìfarajọ-èébú:

Àríṣògún Mọdẹ Ìrẹsà
Ohun mẹ́rìndínlógún ni o jọ́mọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
O ò rí i? N ó pa gbẹ́rẹ́ n ó lọ rèé ké s'ákọ̀pẹ
Bí yóò lọ oko ẹyìn lónìí n ò tíì mọ̀
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
Akọ̀pẹ kọ̀pẹ tán
N ó lọ rèé kẹ́yìn mi
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
Ma ru ẹyìn sẹ́kù
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
Ọ̀túnla màá sa ẹ̀rẹ̀ ẹyìn
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
Ma sẹ́gi wálé
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
Ma pọnmi ẹkù
Kò jẹ́ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ
Ma dána mọ́ ẹyìn lónìí
Kò jẹ kí ọmọ Onírẹ̀sà gbé'lé ọkọ…
(Babalola 2001:106-107)

Oríkì òkè yìí ti fi hàn pé àwọn ìran Arẹ̀sà ni igi ọ̀pẹ lọ́pọ̀lọpọ̀, iṣẹ́ epo ṣíṣe ni ó sì gbájúmọ́ jùlọ láàrin wọn, àwọn ìdílé Arẹ̀sà ni ọmọ elépo ni Mọdẹ, ọmọ ẹlẹ́gbẹ̀rún ọ̀pẹ, gbogbo ìgbà ni wọ́n sì máa ń ná-án-ní èyí torí ó máa ń mu owó wá fún wọn lọ́pọ̀lọpọ̀.

Àmọ́ ó hàn gbangba nínú oríkì òkè yìí pé àwọn ọmọ Arẹ̀sà obìnrin kíí fìdí mọ́ ilé ọkọ wọn. Bẹ́ẹ̀ láwùjọ Yorùbá èébú ni pé kí ènìyàn má ráàyè mójútó ẹbí rẹ̀ tó bí ó ti yẹ. Yorùbá lòdì sí kí lọ́kọláya kọrasílẹ̀, ṣùgbọ́n àwọn obìnrin Arẹ̀sà tó jẹ́ olóríkì kò rí àìlèfarabalẹ̀ nílé ọkọ gẹ́gẹ́ bí ohun ìtìjú, torí wọ́n gbàgbọ́ pé "ṣiṣẹ́ ṣiṣẹ́ nìkan ló lè jàre òsì". Nínú oríkì Arẹ̀sà tí a fàyọ lókè yìí, a o ri pé iṣẹ́ epo ni àwọn ìran Arẹ̀sà yàn láàyò láti kékeré wọn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun ní a sì máa ń mú jáde láti ara igi òpẹ bíi: Epo, Èkùrọ́, Ògùnsọ̀, ìkẹ̀tẹ́ àti ọwọ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ ni ó sì máa ń gbà láti ṣe àwọn nǹkan tí a dárúkọ sí òkè yìí, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó ni ó máa ń ti ibẹ̀ jáde. Tí a bá wo oríkì yìí dáadáa a o rí í pé àwọn obìnrin Arẹ̀sà

gbájú mọ́ iṣẹ́ bẹ̀ẹ̀ ni wọn kò sọ̀lẹ̀, ìmẹ́lẹ́ kò sì ráàyè láyé wọn. Láti kékeré ni àwọn ọmọ Arẹ̀sà ti máa ń mọ̀ nípa iṣẹ́ ìran wọ́n yìí àti owó gegere tí ó ń ti ibẹ̀ jáde, èyí ni kò jẹ́ kí wọn lè ní àmójúkúrò nínú iṣẹ́ náà, torí wọ́n mọ̀ pé ọ̀nà ọlà wọn ni. Ìpèdè àbùkù ni pé àwọn ọmọ Arẹ̀sà kìí gbé ilé ọkọ ṣùgbọ́n ni ìgbàkugbà tí àwọn akéwì tàbí apohùn bá ń ki àwọn ọmọ Arẹ̀sà báyìí ṣe ni wọ́n máa ń yọyì tí wọn yóò sì ti ọwọ́ bọ àpò láti fún akéwì ni owó, nítorí pé oríkì yìí kìí ṣe èébú mọ́ bí kò ṣe ohun iyì àti ẹ̀yẹ torí oríkì yìí fi àwọn ọmọbìnrin Arẹ̀sà hàn gẹ́gẹ́ bí akíkanjú tí ó mú iṣẹ́ ṣíṣe ní ọ̀kúnkúndùn, kì í ṣe èyí nìkàn, akíkanjú tí wọ́n jẹ́ tún jẹ́ kí wọ́n ní owo lọ́wọ́ èyí sì mú wọn jàre òsì. Bákan náà, nítorí pé àwọn ọmọbìnrin Arẹ̀sà múra sí iṣẹ́ wọn, wọn kò wo ojú ọkọ kí wọ́n tó ṣe ohun tí ó yẹ fún àwọn ọmọ wọn tàbí dá ohun rere ṣe. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn obìnrin Arẹ̀sà kìí ṣe alábọ̀ọ̀do wọ́n tó tán láàyè ara wọn. Àwọn akéwì tí ó ń ki àwọn ọmọ Arẹṣà yìí kò fi àwọn ohun tí wọ́n ń sọ nípa wọn tàbùkù wọn bí kò ṣe pé wọ́n fi ń gbóríyìn fún wọn pé wọn mú iṣẹ́ ìran wọn ní ọ̀kúnkúndùn èyí tí ó sì sọ wọ́n di ẹni pàtakì èyí ló sì mú kí wọ́n máa ṣe ògo nínú oríkì yìí tí inú wọn sì ń dùn. Èyí túmọ̀ sí pé ohun tí ó ṣe yọyì tó jẹ́ àyọrísí ohun tí a pè ní èébú máa ń pa àbùkù rẹ́ nínú oríkì.

Ẹ̀rí láti inú àwọn oríkì ìlú ní ilẹ̀ Yorùbá fi hàn pé kì í ṣe inú oríkì orílẹ̀ nìkan ni ìfarajọ-èébú ti máa ń jẹyọ. Nínú oríkì Ìkàrẹ́-Àkókó gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, a rí àpẹẹrẹ ìfarajọ-èébú:

Ọmọ Olókè méjì takọtabo  
Ọmọ àlèwù lewu òkúta  
Ọmọ olóbì pòròpòrò àrokò  
Ọmọ ò tan olùkùn rẹ̀ gun igi gbígbẹ  
Igi gbígbẹ wò ó, olùkùn rẹ̀ wò ó  
Ọmọ asòrò lájòjì sọnù  
Àjòjì forí kó nini òwúrọ̀ (Ògúndánà, 2020)

Nínú oríkì ìlú Ìkàrẹ́ tí ó wà lókè yìí ìlà kẹrin àti ìlà karùn-ún ni a ó kọ́kọ́ ṣàlàye nípa wọn.

Ọmọ ọ tàn olukun rẹ̀ gun igi gbígbẹ  
Igi gbígbẹ wò ó, olùkun rẹ̀ wò ó (Ògúndánà, 2020)

O yẹ kí a kọ́kọ́ mọ̀ pé Olùkùn ni àwọn ìlú Ìkàrẹ́ máa ń pe ọ̀rẹ́ wọn. Ohun tí ìlà kẹrin àti ìkarùn-ún ń sọ nípa oríkì ìlú Ìkàrẹ́ ni pé wọ́n máa ń tan ọ̀rẹ́ wọn gun igi gbígbẹ, tí ọ̀rẹ́ wọn sì máa ń jábọ́ lúlẹ̀ láti orí igi gbígbẹ tí wọ́n tàn án gùn. Oríkì yìí fi ìlú Ìkàrẹ́ hàn gẹ́gẹ́ bí ọlọgbọ́n àti ọlọ́pọlọ pípé. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn kan lè fi ojú ọ̀dàlẹ̀ wò wọ́n. Ní ilẹ̀ Yorùbá àwọn Yorùbá kò fara mọ́ ilẹ̀ dídà èyí ni wọn ṣe máa ń sọ pé "Ẹni bá dalẹ̀ yóò bá ilẹ̀ lọ" èyí nìkan kọ́ wọ́n tún máa ń sọ pé "Èké ní í pẹrú, ilẹ̀ dídà ní í pọ̀rẹ́, alájọbí ní í pa ìyekan tó bá

sebi". Ẹni tí ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò ṣe é gbàgbọ́ ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kìí ṣe ọmọlúàbí. Ní ìgbà tí a bá ń ki àwọn ọmọ Ìkàrẹ́-Àkókó ní oríkì òkè yìí kìí ṣe èébú ṣùgbọ́n a ń ṣe àfihàn wọn gẹ́gẹ́ bí ọlọgbọ́n tí ó ní agbára tí ó sì mèrò torí àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé 'alágbára má mèrò baba ọ̀lẹ ni"

Bákan náà, ìlà ìkẹfà nínú oríkì ìlú Ìkàrẹ́ tún kì wọ́n ní: *ọmọ* a *pòpòrun jàre*. Èyí túmọ̀ sí pé bí wọ́n tilẹ̀ ba ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan jẹ́ tàbí fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ṣòfò, àwọn ni yóò tún padà jàre ènìyàn yòówù tí wọ́n fi nǹkan rẹ̀ ṣòfò tàbí ba nǹkan rẹ̀ jẹ́.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé oríkì yìí farajọ èébú tí ò sì ń fi àwọn ìlú Ìkàrẹ́ hàn bí arẹ́nijẹ, tí wọ́n sì máa ń kọ̀ láti gbà pé àwọn jẹ̀bi tàbí tọrọ àforíjìn lọ́wọ́ ẹni tí wọ́n ṣẹ̀. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá, oríkì yìí ní ìgbà tí a bá ń ki àwọn olóríkì yìí ń fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó gbọ́ lẹ́nu, tí ó sì lè sọ ìdí pàtàkì fún ohunkóhun tí wọ́n bá ṣe. Torí àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé "àìlèsọ̀rọ̀ ni ìbẹ̀rẹ̀ orí burúkú". Àwọn ọmọ ìlú Ìkàrẹ̀ gbọ́n sásá, wọ́n láyà, wọ́n sì lè kojú ohunkóhun láì bẹ̀rù, èyí ni wọ́n ṣe máa ń yọyì ní ìgbà tí a bá ń kì wọ́n ní oríkì yìí.

Ìlà keje oríkì Ìlú Ìkàrẹ́ pè wọ́n ni *ọmọ asorò lájòjì sọnù*, èyí túmọ̀ sí pé àwọn ọmọ Ìlú Ìkàrẹ́ kìí bá àjòjì ṣe tàbí pé wọn kò nìfẹ́ẹ̀ sí àjòjì. Àwọn Yorùbá máa ń fi ìfẹ́ hàn sí àlejò torí wọ́n gbàgbọ́ pé "ìgbín nìkan ni ó ń lọ sí àjò tí ó gbé ilé rẹ̀ dànì", ní èrò àwọn Yorùbá ìrànlọ́wọ́ kò pín sí ọ̀dọ̀ ẹnìkan, èyí ní wọ́n ṣe máa ń kó gbogbo ènìyàn mọ́ra yálà wọ́n jẹ́ ẹni mímọ̀ tàbí àrè.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ènìyàn àwùjọ yóò wo àwọn ọmọ ìlú Ìkàrẹ́ nípasẹ̀ oríkì yìí gẹ́gẹ́ bí ọ̀dàlẹ̀, ẹni tí kò ṣe é fi ọkàn tán, arẹ́nijẹ àti ẹni tí kò nífẹ̀ẹ́ àjòjì ṣùgbọ́n nígbàkugbà tí àwọn apohùn bá ń kì wọ́n ní oríkì yìí, wọn kò fi tàbùkù wọn dípò bẹ́ẹ̀ ṣe ni wọ́n fi ń ṣe àyẹ́sí wọn tí wọ́n sì ń polongo wọn bí ọ̀lọgbọ́n àti olóye ènìyàn tí ó máa ń fi ti àwọn ènìyàn rẹ̀ ṣaájú nínu ohun gbogbo. Èyí sì máa ń jẹ́ kóríyá fún wọn.

Nínú oríkì Àkúrẹ́ bákan náà a ri ìpèdè tí ó farajọ-èébú:

Àkúrẹ́ Olóyèmẹkùn
Ọmọ amúdà sílẹ̀ mógun ẹnu pani
Ọmọkùnrin Àkúrẹ́ toko íbọ̀ wọ́n mágada perin
Ọmọbìnrin Àkúrẹ́ tọjà íbọ̀ wọn mólìlò pẹfọ̀n
Àkúrẹ́ lómi méjì án pèjèèjì l'Àlà
Àlà ṣebí eré sebí ere Àlà domi ọmọ
(Adéléke, 2020)

Ìlà kejì oríkì Àkúrẹ́ tí ó wà ní òkè yìí kì wọ́n gẹ́gẹ́ bí *"ọmọ amúdà sílẹ̀ mógun ẹnu pani"* Ogun ẹnu jẹ́ ogun kan gbòógì tí ó ń fa wàhálà tàbí ìdààmú bá ẹ̀dá ènìyàn ṣùgbọ́n tí wọn kò kíyèsí ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni

pé ogun ẹnu burú ju ogun àdá àti ìbọn lọ. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń pòwe pé *"ogun aláròká pani ju ogun osó àti àjẹ́* lọ". Oríṣìíríṣìí wàhálà tí ogun ẹnu ń mú wá sí ayé ẹ̀dá ènìyàn ni ìjákulẹ̀, àgbákò, ìrẹ̀wẹ̀sì àti ikú òjijì.

Oríkì Àkúrẹ́ tí o wà nínú ìlà kejì oríkì òkè yìí tí ó fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ amúdà sílẹ̀ mógun ẹnu pa ni kì í ṣe èébú rárá. Ní ìgbà tí a bá ń kì wọ́n ní oríkì yìí, a ń fi àwọn olóríkì yìí hàn gẹ́gẹ́ bí alágbára lójú ìjà ni. Ọ̀kọ̀, ìbọn àti ọfà wà lára ohun ìja tí àwọn jagunjagun máa ń ṣàmúlò lójú ogun ní ilẹ̀ Yorùbá, ṣùgbọ́n ní ìgbà tí ìjà bá dójú rẹ̀ tán àwọn jagunjagun tó mọ agbára ọ̀rọ̀ a máa gbé àwọn ohun ìjà wọ̀nyí silẹ̀ tí wọn yóò sì fi agbára ọ̀rọ̀ ṣégun àwọn ọ̀tá wọn lójú ogun. Èyí túmọ̀ sí pé ìgbà tí a bá ń ki àwọn ọmọ Àkúrẹ́ gẹ́gẹ́ bí amúdà sílẹ̀ mógùn ẹnu pani kò jẹ́ ojútì fún wọn rárá, iyì ni wọ́n fi ń ṣe, ohun ìwúrí sì ni pẹ̀lú. Lójú tiwọn àti ní ọ̀gangan ipò àṣà ìpohùn àti ìkíni àwọn akéwì yìí kò fi ìhùwàsí wọn yìí pẹ̀gàn wọn ṣùgbọ́n wón fi ń bu ọlá fún wọn ní, àwọn akéwì yìí rí wọn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó dá ara rẹ̀ lójú, tí ó sì gbójú, gbónu, tí ó sì lóògùn.

Kì í ṣe inú ìhùwàsí àwọn ènìyàn ìlú kan nìkan ni ìfarajọ-èébú tilè jẹ jáde, a máa jẹ jáde nínú ìṣesí wọn náà. Bí àpẹẹrẹ àwọn akéwì máa ń ki Ìkirè bí ẹni tí ó hùwà bí alágànná nígbà mìíràn wọ́n á ní:

Èmi kò réèyàn tò lè fàbùjá ilé Ìkirè hanmọ rẹ̀
Olúfọ́n adé ni yín
Ọmọ aládé ṣẹ́ṣẹ́ẹ̀fun
Olóròlú ọmọ kẹ̀ẹ̀ lagba ro nílé olúfọ́n
Òròlú níyọ̀ nílé ó jàtẹ́
Ó lépo nílé jẹlá ni funfun
Ó rìn hòòhò re balùwẹ̀ lárè
Ó lẹ́ní nílé sùn lórí ẹ̀kán
Èèyàn tó mú baba yín lájẹ̀ẹ́ ò nìrọ́ nínú
Igba orí ni baba yín fi í mẹmu
Ẹ̀jẹ èèyàn ló fi í sorò lárè
(Oyèbámijí:2018:155)

Bí a bá wo ìlà keje sí ìkẹsàn-án nínú oríkí òkè yìí, a ki àwọn Ìkirè gẹ́gẹ́ bi ẹni tí "Ò rin ìhòòhò re balùwẹ̀ lárè". Tí ènìyàn bá fẹ́ wẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá ní ìgbà tí irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ bá dé balùwẹ̀ ni yóò tó bọ́ aṣọ kúrò ní ara ṣùgbọ́n oríkì Ìkirè fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó máa ń rin ìhòòhò lọ sí balùwẹ̀ ní ìlú wọn tí ó ń jẹ́ Àrè. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé bí ènìyàn kan bá dédé bọ́ ara sílẹ̀ tí ó sì ń rìn ìhòòhò, a jẹ́ pé ọpọlọ irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ dàrú ni. Bákan náà ni a kì wọn ní ìlà kẹjọ gẹ́gẹ́ bí "ò lẹ́ni nílé sun lórí ẹ̀kán". Ẹní ni àwọn Yorùbá fi máa ń sùn ní ayé àtijọ́ kí ó tó di pé àwọn ibùsùn oní tìmùtìmù dé. Irúfẹ́ koríko kan ni ẹ̀kàn jẹ́, èyí tí o máa ń gún ni púpọ̀, ki ẹni kan kúrò lórí ẹni láti sùn sí orí ẹ̀kàn túmọ̀ sí ìpọ́njú ńlá. Ní ìgbà tí a bá ń ki àwọn ọmọ Ìkirè gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ń rin ìhòòhò lọ

sí balùwẹ̀ àti ẹni tó fi ẹní sílẹ̀ sùn sí orí-ẹ̀kán, ṣe ni inú wọn yóò máa dùn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìpèdè wọ̀nyi farajọ èébú sìbẹ̀ wọn kì í ṣe èébu torí ìpèdè yìí ṣàfihàn wọn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó máa ń ṣe ohun tó wù wọ́n, lásìkò tí ó wù wọ́n ni. Ní ìgbàkigbà tí àwọn akéwì bá ń ki àwọn olóríkì yìí wọ́n ń fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni pàtàkì tí ó ń ṣe ohun tí ó wù ú, tí kò sì sí ẹni tí yóò bi í léèrè pé báwo ni ó ṣe rí bẹ́ẹ̀, nítorí náà rírìn ìhòhò re balùwẹ̀ wọn àti fífi ẹ̀kan sùn jẹ́ ohun àrà èyí tí ó sì sọ wọ́n di aláràgbàyídá.

Bàkan náà ni ìlà kẹwàá sí ìkejìlá nínú oríkì Ìkirè tí ó wà ní òkè yìí tún farajọ-èébú:

Èèyàn tó mú baba yín lájẹ̀ẹ́ ò nírọ́ nínú
Igbá orí ni baba yín fi í mẹmu
Ẹ̀jẹ̀ èèyàn ló fi í sorò lárè

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹ̀mí àìrí méjì ló wà. Èkínní ni ẹ̀mí àìrí rere ní ìgbà tí èkejì jẹ́ ẹ̀mí àìrí búburú. Àwọn ẹ̀mí àìrí rere ni Òrìṣà/Ìbọ àti Aláṣekù/òkú ọ̀run. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé àwọn ẹ̀mí àìrí rere wọ̀nyí kìí sába bínú sí àwọn ènìyàn ṣùgbọn wọn máa ń dáàbòbò àwọn ènìyàn kúrò lọ́wọ́ àwọn ẹ̀mí àìrí búburú. Àwọn ẹ̀mí àìrí búburú ní tiwọn pín sí ọ̀nà méjì: ènìyàn/ẹlẹ́yẹ/Àjẹ́ àti ajogun, àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú yìí máa ń gba ire ọmọ ènìyàn tí wọ́n sì máa ń yí kádàrá rere àwọn ènìyàn padà sí búburú. Ní ìgbà tí àwọn Yorùbá gbà pé a lè fi ẹbọ tu àwọn ajogun lójú, ìgbàgbọ́ wọn ni pé ẹbọ àti àlọ̀ kò ran àwọn ẹlẹ́yẹ àti pé orí ẹni nìkan ló lè gbani lọ́wọ́ wọn.

Gẹ́gẹ́ bí o ti hàn gbangba pé abẹ́ ìsọ̀rí àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú ni àjẹ́ wà tí àwọn ènìyàn sì kà wọ́n sí asebi ní ilẹ̀ Yorùbá, èyí ni kìí jẹ́ kí àwọn tí ó jẹ́ àjẹ́ yìí gbójú-gbóyà láti sọ pé àjẹ́ ni àwọn bí o tile wù kí agbára wọn tó. Ní ti àwọn ọmọ Ìkirè gbogbo àwọn ènìyàn ni ó ǹ pè wọ́n ni àjẹ́ torí dípò ife ìmumi, igba orí ènìyàn ni baba àwọn Ìkirè fi ń mu ẹmu, tí wọ́n sì ń fi ẹ̀jẹ̀ èèyàn ṣe orò ní Àrè dípò ẹ̀jẹ̀ ẹranko. Àwùjọ rí àwọn ọmọ Ìkirè nínú oríkì yìí gẹ́gẹ́ bí apani, ìkà àti ọ̀dájú ẹdá ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ ṣe ni àwọn akéwì tí ó ń kì wọ́n yìí ń ṣàfihàn wọn bí alágbára, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń fi wọ́n hàn bí akíkanjú, akọni àti aṣàjẹ̀ẹ̀másẹ̀ẹ̀ onígboyà ènìyàn èyí ni ó sì ń jẹ́ kí àwọn ọmọ ìlú Ìkirè máa fò fẹ̀rẹ̀ tí wọ́n yóò sì máa ná akéwì lówó, tóri pé wọn kò rí oríkì wọn yìí gẹ́gẹ́ bí ohun ìtìjú bí kò ṣe ohun àmúyangàn.

Bákan náà, nínú oríkì Ìbàdàn èébú tó rọ̀ mọ́ ìhùwàsí wọn jẹ jáde, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé akíkanjú ni àwọn Ìbàdàn àwọn ìwà kòtọ́ kan máa ń jẹ jáde nínú oríkì wọn. Àpẹẹrẹ àwọn ìwà bẹ́ẹ̀ tó farajọ-èébú tí a fi ń yọyì hàn nínú oríkì ìsàlẹ̀ yìí:

Ìbàdàn ọmọ ajòrosùn
Olúyọ̀lé ọmọ afikarahun fọ́ọri mu
Ọmọ fikàn nílé

Ọmọ fìkàn lójú ogun
Ọmọ adìíléè dogun
Ọmọ-a-gbọ́jọ́-ogun-sọ̀dí-wúkẹ́
Ọmọ ogun lọ́sàn-án
Olè tó bá dòru
Ogun àjààwẹ̀yìn, ò ti múlé Ìbàdàn wù mi
Ogun ojoojúmọ́ ló múlé baba wọn súmi lọ
Ìbàdàn kìí báni sọ̀rẹ́ láì rán ni lọ sójú ogun
Ìjà ìgboro làrùn Ìbàdàn
(Oyèbámijí 2018:176)

Bí a bá wo oríkì òkè yìí ó hàn gbangba pé ogun jíjà ti di bárakú fún àwọn Ìbàdàn torí pé gbogbo ìgbà ni wọ́n fi máa ń múrasílẹ̀ fún ogun èyí ni wọ́n ṣe ń kì wọ́n ni "ọmọ adìílẹ̀ dogun" wọ́n tilẹ̀ tún ń kì wọ́n ni "ọmọ a gbọ́jọ́ ogun sọ̀ di wúkẹ́" èyí túmọ̀ sí pé ogun jíjà kò jọ wọ́n lójú tí a bá wá pe àwọn ọmọ Ìbàdàn ni arógunyọ̀ tàbí arógunmátìdí a jẹ́ wí pé a kò jẹ ayọ̀ pa, èyí sì fi wọ́n hàn bí akọni ni. Ní ìgbà tí àwọn apohun bá sì ń kì wọ́n ní oríkì yìí inú wọn máa ń dùn ni pé àwọn jẹ́ akíkanjú. Pé ogun jẹ́ bárakú fún àwọn Ìbàdàn tàbí pé wọ́n jẹ́ adìílẹ̀ dogun kìí ṣe èébú ṣùgbọ́n ìwà olè tí wọ́n fi kún dídìílẹ̀ dogun ní ó fa ìpèdè ajẹmọ́ èébú ní ìlà keje sí ìkẹjọ.

Ní ìlà keje àti ìlà kẹjọ oríkì Ìbàdàn tí a sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ lókè a kì wọ́n báyìí:

Ọmọ ogun lọ́sàn-án
Olè tó bá doru

Àwọn Yorùbá koriira olè jíjà, wọ́n sì gbàgbọ́ pé olè kìí ṣe ọmọlúàbí, bí wọ́n bá pe ẹnìkan ni olè gbogbo àwọn ẹbí olè yìí gan-an ni wọ́n ń bú papọ̀, ẹ̀tẹ́ tàbí àbùkù ẹni tí ó bá ja olè ní ilẹ̀ Yorùbá jẹ́ títí ayé, èyí ni wọ́n ṣe máa ń pa òwe pé "ẹni tó bá jalè lẹ́ẹ̀kan, tó bá da àrán borí, aṣọ olè ló dà bora". Ní ìgbà tí wọ́n bá n ki oríkì Ìbàdàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ ogun lọ́sàn-án, olè tó bà doru kìí bá wọ́n nínú jẹ́ ṣúgbọ́n ṣe ni ó máa n mú orí wọn wú, tí ó sì máa ń mú inú wọn dùn. Torí olè jíjà wọn kì í ṣe ti alọ́nilọ́wọ́gbà ṣùgbọ́n ti gbígbé arẹwà obìnrin tí ó jẹ oju ní gbèsè ni, àti kíkó ẹrú àti ẹrù bọ̀ láti ojú ogun tí wọ́n ti ja àjàṣẹ́gun ni.

Nì ìlà kejìlá tí ó gbẹ̀yìn oríkì náà, a kí àwọn Ìbàdàn gẹ́gẹ́ bí oníjà:

## Ìjà ìgboro làrùn Ìbàdàn

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé "Ìjà kò dọlà àti pé orúkọ lásán ló n sọ ni". Wọ́n tún gbàgbọ́ pé ìjà kìí bímọ ire, èyí ni wọ́n ṣe máa ń làkàkà láti gbé ní àlàáfíà pẹ̀lú èniyàn gbogbo. Oríkì òkè yìí ní ojú àwọn ènìyàn àwùjọ fi àwọn ọmọ Ìbàdàn hàn gẹ́gẹ́ bí aríjàgbá àti oníjàngbọ̀n ṣùgbọ́n àwọn akéwì àti àwọn

olóríkì kò rí bẹ́ẹ̀ ní ìgbà tí a bá ń kì wọ́n pé ìjà ìgboro làrùn Ìbàdàn. Ohun tí àwọn akéwì ń fi oríkì yìí sọ ni pé àwọn ọmọ Ìbàdàn kọ ìwọ̀sí àti pé kò sí ibi tí wọn kò ti le jà fún ẹ̀tọ́ wọn. Èdè àwọn àti akéwì ye ara wọn, bí ó ti ń kì wọ́n yìí ni orí wọ́n máa ń wú ni ti wọn yóò sì máa fẹlá, tí wọn yóò máa na onílù tàbí akéwì tí ó bá ń kì wọ́n ní owó.

Ìfarajọ-Èébú tún máa ń jẹyọ nínú àwọn oríkì àbisọ, àmútọ̀runwá, àlàjẹ́ àti ìnagijẹ tí a máa ń fún àwọn ènìyàn. Díẹ̀ lára àwọn oríkì ajẹmórúkọ tí a sàyàn ni oríkì Oyèrìndé, Ìgè, Aasà àti Òjó - Nínú àwọn oríkì yìí a rí ìpèdè to farajọ èébú tó rọ̀ mọ́ ìṣe àti ìhùwàsí àwọn olóríkì tó jẹmórúkọ náà, bí àpẹẹrẹ nínú oríkì Oyèrìndé èébú tí ó jẹ́ mọ́ ìṣesí ló jẹyọ. Gbogbo ẹni tí ó ń jẹ́ àlàjẹ́/àdàpè yìí ni wọ́n sì ń kì bẹ́ẹ̀, bákan náà nínú oríkì Ìgè a rí èébú tí ó jẹ mọ́ ìbí rẹ̀, ewu tó rọ̀ mọ́ ìbí rẹ̀ tí àwọn Yorùbá sọ dí ohun tí wọ́ fí ń ṣàfihàn rẹ̀.

Ní báyìí a ó ṣe àgbéyẹ̀wò ìfarajọ-èébú nínú oríkì àlàjẹ́ ti Oyèrìndé.

Odù, ọmọ alágbára
Ò jẹ gbẹ̀gìrì sọ aṣọ egbèje nù
Ò jà níbí t'ó gbé j'ẹ̀kọ àná
Odù ọmọ alágbára
(Adéoyè 1982:52)

Ní ìlà keji oríkí Oyèrìndé a kì í ní "ò-jẹ-gbẹ̀gìrì-sọ-aṣọ-egbèje-nu", tí a bá wò ó dáradára owó gbẹ̀gìrì kéré púpọ̀ sí aṣọ egbèje, ìlà keji yìí farajọ-èébú torí ni ìlà kìnní a ti pe Oyèrìndé ní ọmọ alágbára ṣúgbọn ní ìlà keji a sọ pé ò-jẹ-gbẹ̀gìrì-sọ-aṣọ-egbèje-nù. Ìgbagbọ́ àwọn Yorùbá ni pe "alágbára má mèrò baba ọlẹ ni. Ìpèdè yìí kì í ṣe èébú ṣe ló fi Oyèrìndé hàn gẹ́gẹ́ bí ẹdá tí ó fẹ́ràn oúnjẹ púpọ̀, èyí túmọ̀ sí pé kò lè fi inú rẹ̀ seré tàbí fi ebi pa ara rẹ̀ sebí àwọn Yorùbá bọ̀ wọ́n ni "ebi kì í wọnú kí ọ̀rọ̀ mìíràn wọ̀ ọ́.

Ní ìlà kẹta, a tún pè ní "ò jà níbi tó gbé jẹ̀kọ àná", ohun tí àwọn Yorùbá máa ń sọ ni pé "ẹni tí a ṣe lóore tí kò dúpẹ́, bí ọlọ́ṣà kò ni lẹ́rù lọ ni àti pé "ẹni tí a ṣe lóore ẹgbàfà tí kò dúpẹ́, ó fagi dína egbèje. Ohun tí àwọn òwe méjèèjì òkè yìí ń tọ́ka sí ni pé a nílò láti dúpẹ́ oore. Ojú abaramooreje ni àwùjọ fi ń wo Oyèrìndé nítorí ó jà níbi tí ó ti jẹ̀kọ àná, èyí túmọ̀ sí pé ko rántí ohun tí wọ́n ṣe fún un mọ. Ní ìgbàkugbà tí àwọn apohùn bá ń ki Oyèrìndé ní oríkì yìí kì í ṣe èébú mọ́ ṣùgbọ́n ṣe ni wọ́n ń kan sáárá sí i gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ọkàn tí ara rẹ̀ tí ohunkóhun kò sì lè dí i lọ́wọ́ ohun tí ó bá fẹ́, èyí sì ń tọ́ká sí Oyèrìndé gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ìpinnú àti alágbára.

Ọmọ tí a bí tí ó jé pé ẹsẹ̀ rẹ̀ ni ó kọ́kọ́ jáde kí orí tó jáde ni a ń pè ní Ìgè, orúkọ yìí sì jẹ́ orúkọ àmútọ̀runwá. Ní ilẹ̀ Yorùbá ìgbà tí aláboyún bá fẹ́ bímọ ní ọjọ́ ìkúnlẹ̀ orí ni ọmọ máa ń mú wáyé ṣùgbọ́n ní ti ọmọ tí a ń pè ní Ìgè ẹsẹ̀ ni ó kọ́kọ́ ń nà síta. Ọ̀pọ̀ aláboyún tí ọmọ bá fẹ́ kọ́kọ́ mú ẹsẹ̀ wáyé ló máa ń ni ìfarapa, ní ìgbà tí díẹ̀ nínú wọn tí orí kò bá kó yọ, máa ń gba ibẹ̀ jẹ́ ìpè

Olódùmarè, fún ìdí èyí eléwu ọmọ ni àwọn Yorùbá ka Ìgè sí. Ní báyìí, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò bí ìpèdè tó farajọ-èébú ṣe jẹyọ nínú oríkì Ìgè:

Ìgèlàdùbí kẹkẹ-ńsọgbà
Róńdó bí eyin ọ̀kánhán
Ẹni tó bẹ Àdùbí níṣẹ́
Ara rẹ̀ ló bẹ̀
Àdùbị́ kò ní jẹ́, bẹ́ẹ̀ ni kò ní kọ̀
Àdùbí tó ní bí ìyá lè kú, kó kú
Bí baba lè bẹ, kó bẹ
Ohun t'Ádùbí ó jẹ kò wọn
Elẹ́gédé ḿbẹ l'óko
Gbọ̀rọ̀ Àdùbí ḿbẹ lákìtàn (Adéoyè 1982:42)

Tí a bá wo oríkì Ìgè láti òkè dé ìsàlẹ̀ a ó rí i pé oríkì yìí ṣàfihàn Ìgè gẹ́gẹ́ bí olóríkunkun àti aláìgbọràn ọmọ. Ìlà kẹfà àti ìkeje pẹ̀lú fi Ìgè Àdùbí hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀dájú ọmọ tí kò bìkítà bí ìyá tàbí bàbá òun bá kú torí ọ̀nà àrà tí ó gbà wáyé èyí tí ó ṣe é ṣe kó mú ìjàmbá bá ìyá rẹ̀. Gbogbo àwọn èébú ọ̀kanòjọ̀kan tí àwùjọ rí pé ó ṣodo sínú oríkì Ìgè yìí yípadà dí ohun àmúyangàn ní ìgbà tí àwọn apohùn bá fi ń kì í torí ó fi Ìgè hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọ pàtàkì tí ó gba ọ̀nà àrà wáyé, tí ìyà àti bàbá rẹ̀ kò sì ní agbára láti yí ọ̀nà tí ó fẹ́ láti gbà wáyé padà. Bí wọ́n bá ṣe ń kì í ní oríkì yìí ni inú rẹ̀ yóò máa dùn tí ayọ̀ yóò sì gba ọkàn rẹ̀.

Òjó ni ọmọ tí ó gbe ibi kọ́rùn wá ayé ní ìgbà tí a bí i. Ní ìgbà tí ọmọ náà bá jẹ́ ọkùnrin ni a máa ń sọ ọ́ ní Òjó ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ obìnrin ni Àìná ni wọn yóò sọ ọ́. Bákan náà ni ìpèdè tó farajọ-èébú jẹyọ nínú oríkì Òjó:

Òjó jẹngẹtíèlè
Ajagun bí akúra
Òjó kò sí nílé ọmọ adìyẹ dàgbà
Òjó tàjò dé, ọmọ adìyẹ kù fẹ́nfẹ́
Òjó abìjà bí ẹni tarìn
Òjó ajagun lójú ológun
Òjó agbógungbóró, aránti ọ̀rọ̀ ẹ̀yìn
Òjó àbàbà-tiribà
Òjó alágada ogun
(Dárámọ́lá àti Jẹ́jẹ́ 2005:68)

Ìlà kejì oríkì Òjó tí ó wà ní òkè yìí fi hàn gẹ́gẹ́ bí oníjàngbọ̀n tàbí aríjàgbá, ní ìlà kẹta oríkì náà a kí Òjó pé kò sí nílé, ọmọ adìyẹ dàgbà, èyí túmọ̀ sí pé àlàáfíà jọba nítorí pé Òjó kò sí ní ilé. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé oníjàgíjàgan tàbí oníjà ènìyàn kìí ṣe ọmọlúàbí, fún ìdí èyí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni wọ́n máa ń

kíyèsára tí wọ́n sì máa ń sá tàbí yàgò fún jàgídíjàgan. Àwọn Yorùbá tún máa ń sọ pé "ìjà kò dọlà, orúkọ lásán ni í sọ ni". Ní ti Òjó ajagun bí akúra àti alágada ogun ni a mọ̀ ọ́n sí torí gbogbo ìgbà ní ó fi máa ń wá wàhálà kiri ṣùgbọ́n ní ìgbà yòówù tí a bá ń kí òjó ni àwọn oríkì rẹ̀ tí ó fi ìwà àti ìṣesí rẹ̀ hàn èyí tí ó farajọ-èébú yìí kì í ṣe èébú mọ́ akéwì ń fi Òjó hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó kọ ìwọ̀sí ni àti ẹni tí kì í rẹ̀ láti jà fún ẹ̀tọ́ rẹ̀ ní gbogbo ìgbà.

Ọmọ tí a bí, tí ó wẹ́, tí ó sì máa ń ké tantan ní alaalẹ́ ni a máa ń sọ ni Aasà. Ọmọ mìíràn ní ilẹ̀ Yorùbá tí ó ní àbùdà kan náà pẹ̀lú Aasà ni Òní. Ìyàtọ̀ kan gbòógì tí ó wà ní àárin Aasà àti Òní ni pé, tọ̀sán tòru ni Òní máa ń ké ṣùgbọ́n alaalẹ́ nìkan ni Aasà máa ń ké ní tirẹ̀. Nínú oríkì Aasà tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí ìfarajọ-èébú jẹyọ nínú ìhùwàsí rẹ̀:

Oníbúadé
Oníbú adé òkòtòlomù
Apẹkọrọ yílùú ká
A-gbéyàwó má sàna
Ọ̀rọ̀rọ̀ a rọ mọ sítẹ̀ẹ́
Ò gbé ìmọ̀le mì t'agbádá t'agbádá
Ìmọ̀le ń ṣe káì-káì
Oníbúadé ń ṣe máa-ká-lọ
Akọ oṣù tí í lé láàárín òru
(Adéoyè 1982:56)

A ki Aasà gẹ́gẹ́ bí apẹkọrọ yílùú ká, èyí túmọ̀ sí pé wọ́n máa ń gbé e káàkiri ni láti rẹ̀ ẹ́ lẹ́kún ní ìgbà tí ó bá bẹ̀rẹ̀ ẹkún rẹ̀ ní sísun. Bákan náà, ní a kì í gẹ́gẹ́ bí akọ oṣù tí í lé láàárín òru, alaalẹ́ ni oṣù máa ń lé ní ilẹ̀ Yorùbá ní ìgbà tí àwọn ènìyàn yóò ri, tí wọn yóò sì máa sọ pé oṣù ti lé sójú ọ̀run. A fi Aasà wé akọ oṣù torí pé ní ìgbà tí gbogbo àwọn ènìyàn bá ti fi àárọ̀ àti ọ̀sán ṣe iṣẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá ṣe ni wọ́n máa ń fi òru sùn tí wọn yóò fara lélẹ̀ láti sinmi, torí kí ara wọn lè jí pépé láti tún lọ sí ẹnu iṣẹ́ òòjọ̀ wọn ní ìgbà tí ojú bá mọ́. Aasà ní tirẹ̀, kìí sùn lóru, òru gan-an ni ó máa ń ké tantan, tí kò sì ní jẹ́ kí àwọn ara ilé yòókù sùn. Ní ìgbà tí àwọn akéwì bá ń ki Aasà tí wọ́n sì ń tọ́ka sí gbogbo àwọn onírúurú ìwà rẹ̀, kìí ṣe èébú rárá ṣùgbọ́n ṣe ni wọ́n ń ṣàpọ́nlé rẹ̀ pé ó jẹ́ alágbára àti pé ó kápá àwọn ènìyàn àti ohun gbogbo tí ó wà ní àyíká rẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé ohun tí Aasà bá fẹ́ ni wọ́n gbọdọ̀ bá a fẹ́, èyí sì fi hàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá pàtàkì láwùjọ.

## Ìkádìí

Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, ọ̀kan pàtàkì tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ni oríkì jẹ́, nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí a ti ṣe àgbéyẹ̀wò ìfarajọ-èébú nínú àwọn àsàyàn oríkì Yorùbá. Àrífàyọ tí a se nínú iṣẹ́ yìí ti fi hàn pé àwọn ìpèdè tí ó

farajọ-èébú máa ń jẹyọ nínú ìṣesí àti ìhùwàsí olóríkì ìbáà ṣe ènìyàn, ìlú tàbí orílẹ̀ àti pé kìí ṣe dandan kí ẹni tí wọ́n ń kì hu àwọn ìwà yìí gan-an nígbà mìíràn pàápàá nínú orìkì alàjẹ́ àmọ́ torí pé ó ń jẹ́ oríkì ajẹmórúkọ yìí wọ́n a fi èébú yìí kì í, inú rẹ̀ yóò sì dùn. Ó tún hàn gbangba pé ìfarajọ-èébú ní ọ̀gan-gan ipò oríkì kìí ṣe ohun tó lòdì, ní ọ̀pọ̀ ìgbà dípò kí wọ́n rí i bí àbùkù, ohun àmúsògo ni. Ìwádìí yìí tún fi hàn pé èébú ní í ṣe pẹ̀lù àṣà torí ohun tí ó jẹ́ èébú nínú àṣà kan lè má jẹ́ èébú nínú àṣà mìíràn. Bákan náà ní ó tún hàn pé ìfara-jọ-èébú nínú oríkì máa ń jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí àwọn olóríkì fi máa ń fi ìmọ̀sílára hàn. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ó máa ń so wọ́n pọ̀ pẹ̀lú àwọn tó ṣẹ̀dá wọn, ìdí nìyí tí àwọn nǹkan akọni tí àwọn babańlá wọn ti ṣe se jẹ́ ohun àmúyangàn. Ohun tí ó hàn gbangba nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ tó farajọ-èébú àti àwọn ọ̀rọ̀ àbùkù tí àwọn ènìyàn máa ń sá fún tàbí korò ojú sí ní àwùjọ Yorùbá ní ìgbà gbogbo, ní ìgbà tí wọ́n bá jẹyọ gẹ́gẹ́ bí oríkì ohun ọlá àti iyì ni. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé àwọn àṣà àti èrò Yorùbá nípa èébú àti àbùkù máa ń yípadà ní ìgbà tí a bá ṣàmúlò wọn gẹ́gẹ́ bí oríkì ní ilẹ̀ Yorùbá, àwọn ìpèdè tí ó fara-jọ-èébú ní ọ̀gangan ipò oríkì kì í ṣe àbùkù ṣùgbọ́n àfihàn ìtàn ìran àti àkọsílẹ̀ ìṣe akọni àwọn olóríkì èyí tí ó yẹ fún ìwúrí, àmúsògo àti àmúyangàn.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C.L. *Àṣà̀ àti Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: University Press Limited, 1980.

Adeoye, C.L. *Orúkọ Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Limited, 1982.

Adéjùmọ̀, A.G. and Oyèbámiji̇́, A.K. "Animism in Yorùbá lineage poetry". IJLL: Ife Journal of Languages and Literatures 5:1 (2019):60-77.

Àjàyí, W.B. "Oríkì Orílẹ̀ Àwọn Aládé Àríwá Èkìtì ní Ìpínlẹ̀ Òǹdó". Unpublished M.A. Project, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀ (Nigeria) 1984.

Àjàyí, O.T. "Àgbéyẹ̀wò Ojú Amúwayé Yorùbá Nípa Ẹranko nínú Àsàyàn Lítíréṣọ̀ Alohùn". Unpublished Doctoral Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀, (Nigeria), 2014.

Ajíbádé, G.O. A Sociological Analysis of Yorùbá Male Personal Oríkì (Oríkì Àbíṣọ) *Ifẹ̀ Journal Theory and Research in Education (IJOTRE).* Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀ , 6 (1) pp 90-96. 2001.

Ajíbádé, G.O. Finding Female Voice: A Socio-Cultural Appraisal of Yorùbá Nuptial Poetry, Rudiger Koppel:Koin Bonn, Germany, 248 pages (ISBN 978-3-89645-282—5). 2009.

Akínselóyìn, A. "Contradiction in Oríkì". Unpublished M.A Project, University of Ibadan, Ibadan (Nigeria) 2014.

Akínyẹmí, A. "Ìlò Oríkì Láwùjọ Ìlú Ọ̀yọ́". Unpubslihed Ph.D Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀ (Nigeria) 1991.

Akínyẹmí, A. Oríkì:The Essence of Yorùbá Religious Literature in Yorùbá Ideas. *A Publication of Glendora International* Lagos, Nigeria. Vol 1 Nọ 1, (1997): Pp 184-188.

Akínyẹmí, A. The Role of Oríkì in Yorùbá Traditional Religious Poetry in *Journal of Religion in Africa,* University of Leeds. 1999.

Akínyẹmí, A. "Positive Expression of Negative Attribute: An Aspect of Yorùbá Court Poetry". *Research in African Literatures 35:3* (2004): 93-111.

Applauso, N. Curses and Laughter: The Ethics of Political Invective in the Comic Poetry of High and Late Medieval Italy. Unpublished Ph.D Thesis in the Department of Romance Languages, University of Oregon, Eugene. 2010.

Aransi, A.O. "Ọ̀wọ̀ Praise Poetry: A Hermeneutics Analysis" Thaga: *A Journal of African Studies* 10:1 (2019) 53-70.

Atilade, E.A. *Ìwé Oríkì Àwọn Orílẹ̀ Yorùbá*. Lagos: New Nigeria Press, 1963.

Awé, B. "Notes on Oríkì and Warfare in Yorùbáland" Abimbola (Ed) Oral Tradition: Poetry in Music, Dance and Drama. Ifẹ̀ African Languages and Literatures Series, Department of African Languages and Literatures, University of Ife (Nigeria) 1975.

Awé, B. "Praise Poems as Historical Data: The Example of the Yorùbá Oríkì in Africa. Journal of the International African Institute 44: (1974) 331-349.

Babalọlá, A. The Content and Form of Yorùbá Ìjálá. Clavendon Press, Oxford, 1966.

Babalọlá, A. *Àwọn Oríkì Orílẹ̀* M*ẹ́tàdínlọ́gbọ̀*n. Lagos: Longman Nigeria Limited, 2001.

Babáyẹmí, S.O. *Content Analysis of Oríkì Orílẹ̀*. Ibadan: Institute of African Studies, 1988.

Barber, K. "Documenting Social and Ideological Change through Yorùbá personal oríkì: A stylistic Analysis". *Journal of the Historical Society of Nigeria* 10:4 (1981).

Barber, K. "Yorùbá Oríkì and Deconstructive Criticism" *Research in African Literatures* 15:4 (1984) 497-518.

Barber, K. *Oríkì*, History and Criticism. Birmingham: Birmingham University Press, 1987.

Barber, K. *Oríkì*, Women and the Proliferation and Merging of *Orìṣa,* Africa: *Journal of the International African Institute*. Vol 60, No 3 (1990), pp 313-337.

Barber, K. *I could Speak Until Tomorrow: Oríkì*, Women and the past in a *Yorùbá* Town. Edinburgh: Edinburgh University Press, 1991.

Bariki, I. L'univers linguistique de l'injure en francais UNAD Studies in Language and Literature 4 (1) (2011) Pp 35-42.

Bariki, I. l'injure enfrancais et en yorouba: inventaire et compentaires In: DD Kiwpole, I. Bariki (Eds): Applied Social Dimensions of Language Use and Teaching in West Africa, Cape Coast: University of Cape Coast Press (2009) Pp 35-42.

Beir H. and Gbàdàmọ́sí, B. *Yorùbá* Poetry. London: Cambridge University Press, 1959.

Bọ́lárìnwá, A.O. "Recreation of Oral Poetic Genres in Selected Yorùbá Home-Video Films". *Africa Focus* 32.1 (2019): 13-35.

Bọ́lárìnwá, A.O. "Oral Tradition as Tool for Teaching Morality in the Yorùbá Society" In *Religion, Ethics and Development* a Festscrift in Honour of Prof. Akpenduun Dzurgba, ed. J.K Àyántáyọ̀, 70-87. Ìbàdàn (Nigeria): Hope Publications. 2019.

Dáramọ́lá, O àti Jẹ́jẹ́, A. *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà* Ilẹ̀ *Yorùbá*. Ìbàdàn:Oníbọnòjé Press (Nig) Ltd,
2005.

Finnegan, Ruth. *Oral Literature in Africa*. Nairobi: Oxford University Press, 1970.

Finnegan, Ruth. *Oral poetry: Its Nature, Significance and Social context*. Bloomington: Indiana University Press, 1977.

Gbàdàmọ́sí, B. *Oríkì*. Ìbàdàn: Mbiti Publishers, 1961.

Kalihu, R.O. "Between Tradition and Record: A search for the Legendary Woodcarers of Old Oyo" UFUHAMU: *A Journal of African Studies.* Vol (1992) page

Klein, William W, Bhomberg, Graig, L àti Hubbard, Robert. *Introduction to Biblical Interpretation.* United States of America: World Inc, 1993.

Kodah, M. The Aesthetics of Invective: Reflections on the Use of Verbal Violence in the Suns of Independence of Ahmadou Kourouma. IOSR *Journal of Humanities and Social Sciences*, 3 (5) (2012) 01-08.

Lasebikan, E.L. *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Yorùbá*. Lagos: Longman Nigeria Limited, 1958.

Lindon, J. "Oríkì Òrìṣà: The Yorùbá Prayer of Praise". *Journal of Religion in Africa* 20:2 (1990) 205-224.

Ogundeji, P.A. *Introduction to Yorùbá* Oral Literature. External Studies Programme, Adult Education Department, University of Ibadan, Ibadan Nigeria. (1991).

Ogundeji, P.A. "Yorùbá Oral Poetry Classification: A case of Unity in diversity. Iṣẹṣe: Ibadan *Journal of Folklore* 2:1 (2000).

Ọlájubù, O. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Lagos: Longman Nigeria Plc, 1978.

Olatunji, O. Classification of Yorùbá Oral Poetry. In Yorùbá Language and Literature. *A Afoláyan ed.* Ibadan: Oxford University Press, 1969.

Olatunji, O. *The Yorùbá* Oral *Poets and His society. Research in African Literatures*. 10:2 (1979) 179-207.

Olátunji, O. *Features of Yoruba Oral Poetry*. Ibadan: Oxford University Press, 1984.

Olukoju, E. "The place of chants in Yorúbá Traditional Oral Literature". Unpublished Doctoral Thesis, University of Ibadan, Ibadan (Nigeria) 1978.

Olúnládé, T. Ìlò Oríkì Nínú Ìwé Ìròyìn Yorùbá. *LÁÀŃGBÀSÀ: Jọ́nà Iṣẹ́ Akádá ní Èdè Yorùbá*. Nọ11, (2005) Pp 23-54.

Oparinde, K.M, Makhubu, R.L and Bariki, I. A Comparative Socio-Semiotic Perspectives of Invectives in Two African Languages: Isizulu and Yoruba, *Journal of Social Sciences*, 52:1-3, (2017) 14-26.

Ramm, B. Protestant Biblical Interpretation. Grand Rapids: Baker Book House, 1991.

Riccocur, Paul. *From Text to Actions: Essays in Hermeneutics II*. Evanstion: Northwestern University Press, 1991.